# A ṢE KRISTI LOGO NIPA IJIYA

## Heberu 2: 1-18

## ẸKỌ 433—FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Nitori ẹnikẹni ti o ba nṣe ifẹ Baba mi ti mbẹ li ọrun, on na li arakunrin mi, ati arabinrin, ati iya mi" (Matteu 12:50).**

Paulu Apọsteli tun sọ ọrọ nipa awọn angẹli ninu ẹkọ yii. O fi han bi Jesu ti ga pupọ ju awọn angẹli lọ, ati pẹlu bi awọn ẹni irapada -- awọn ọmọ Ọlọrun yoo ti ni ogún ti o pọ ju ohunkohun ti awọn angẹli le ni lọ.

Ọlọrun ti fi agbara fun Jesu lati ṣe akoso ohun gbogbo ninu ayé, "Iwọ fi ohun gbogbo sabẹ ẹsẹ rẹ̀" (Heberu 2:8). Bi o ba ri bẹẹ, ki ni ṣe ti Jesu fi wá sinu ayé ti o si jẹ ki awọn eniyan kan Oun mọ́ agbelebu? O sọ fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ, "Nitorina ni baba mi ṣe fẹran mi, nitoriti mo fi ẹmí mi lelẹ, ki emi ki o le tún gbà a. Ẹnikan kò gbà a lọwọ mi, ṣugbọn mo fi i lelẹ fun ara mi" (Johannu 10:17, 18). O ṣe dandan fun Un lati kú ki o ba le san igbese irapada ọmọ eniyan. Nitori ifẹ Jesu ni lati kú fun wa, awa ki yoo tun jiya awọn ẹ̀ṣẹ wa mọ́, bi a ba ronupiwada ti a si bẹ Jesu pe ki o dariji wa.

### Ọba Awọn Ọba

Ṣugbọn ni opin akoko yii, ti Jesu ba gba gbogbo aṣẹ si ikawọ Rẹ̀, Oun yoo sọ gbogbo ọba ati awọn ada-nikan-paṣẹ kalẹ, Oun yoo si fi ododo ṣe akoso ayé. Gbogbo awọn eniyan ti wọn si ti jẹ oloootọ si I yoo ṣakoso pẹlu Rẹ̀, kò si eniyan buburu kan tabi eṣu kan ti yoo le duro niwaju Jesu. Oun yoo ṣe akoso awọn ti o gbọran si I pẹlu ifẹ ṣugbọn awọn wọnni ti o ṣọtẹ si I ni Oun yoo ṣe akoso pẹlu ọpa irin. Egun ti ó wà lori ẹda gbogbo ni a o mú kuro, eniyan yoo si tun ni ipá lori gbogbo ẹranko buburu.

Awọn angẹli ni ipin ninu fifi ofin fun ni lori oke Sinai. Ofin naa le pupọ to bẹẹ ti a maa n jẹ awọn eniyan ni ìyà nigbakigba ti wọn ba ṣe aigbọran si i. Ìyà ti wọn n jẹ si le pupọ. Wọn le pa awọn ọmọde fun lilu awọn obi wọn. Ikú ni iya fun ṣiṣe iṣẹ ni ọjọ isinmi. Bi ijiya ba daju ti o si le to bẹẹ ni igba ofin, bawo ni ijiya yoo ha ti pọ to ni opin akoko Oore-ọfẹ yii, bi awa ba kọ̀ lati pa aṣẹ Jesu mọ́ Ẹni ti O san gbese nlá nlà bẹ́ẹ̀ fun igbala wa!

Ki i ṣe kiki pe aigbọran yoo fa ijiya, ṣugbọn kikuna lati sin Oluwa pẹlu yoo fa ijiya ayeraye. Boya ẹni kan n gbé igbesi-ayé rere laaarin awọn aladugbo ati ọrẹ rẹ̀, kò tilẹ ṣe ohunkohun ti o le pa wọn lara; ṣugbọn bi ohun ko ba di atunbi gẹgẹ bi ilana ẹkọ Bibeli, iru ẹni bẹẹ yoo lọ sinu ègbé ayeraye.

Igbala yii tobi to bẹẹ gẹẹ ti gbogbo awọn wolii sọ nipa rẹ̀. Awọn angẹli pẹlu n fẹ wo o. Ọna wo ni Jesu gbà ki o to le ra ọmọ eniyan pada? O yàn lati san gbese naa nipa tita Ẹjẹ Rẹ silẹ lati ṣetutu fun ẹ̀ṣẹ. Ko ha yẹ ki awa mọ riri ohun ti Jesu ṣe? O ṣe e nitori Oun fẹran wa nigba ti awa jẹ ẹlẹṣẹ. Oun fẹran lati kú fun awọn ọta Rẹ.

### Wiwaasu Ihinrere

Jesu tikara Rẹ kede ihin igbala nigba ti O wà ni ayé. O waasu pe: "A kò ṣe alaitún nyin bí" (Johannu 3:7). O wi pe: "Ẹ wá sọdọ mi, gbogbo ẹnyin ti nṣíṣẹ, ti a si di ẹrù wuwo le lori, emi o si fi isimi fun nyin" (Matteu 11:28). Ni igba miiran O wi pe: Ẹ ronupiwada, ki ẹ si gbà ihinrere gbọ́" (Marku 1:15). Ki O to pada lọ si ọrun, O paṣẹ fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ pe ki wọn waasu ihinrere: "Ẹ lọ si gbogbo aiye, ki ẹ si ma wasu ihinrere fun gbogbo ẹda. Ẹniti o ba gbagbọ́, ti a ba si baptisi rẹ̀ yio là; ṣugbọn ẹniti kò ba gbagbọ́ yio jẹbi" (Marku 16:15, 16). Awọn Apọsteli ati pupọ ninu awọn ọmọ-ẹyin gbọran, wọn si lọ si ibi gbogbo wọn n waasu, "Oluwa si mba wọn ṣiṣẹ, o si nfi idi ọ̀rọ na kalẹ, nipa àmi ti ntẹ̀le e" (Marku 16:20). Nitori naa, "awa o ti ṣe là a, bi awa kò ba nani irú igbala nla bi eyi?" (Heberu 2:3).

### Rẹlẹ Ju Awọn Angẹli Lọ

Lẹyin ti o ti sọ fun wa bi Jesu ti ga ni ọla tó, Paulu sọ pe a da A rẹlẹ diẹ ju awọn angẹli lọ. Bawo ni eyi ṣe ri bẹẹ? Gbogbo awọn angẹli ni Ọrun n foribalẹ fun Un wọn si n sin In. Ko si ọ̀kan ninu wọn ti o yẹ lati kú fun ẹlẹṣẹ. Jesu rẹlẹ ju awọn angẹli ni ti pe O di eniyan O si kú -- ṣugbọn fun akoko kukuru ni.

Bi o ba ṣe pe Jesu wá si aye ni iri angẹli ni, Oun ki ba ti kú. Awọn angẹli ko le kú. Nitori bẹẹ Jesu wá gẹgẹ bi "irú ọmọ Abrahamu" eniyan. A bi I sinu ayé yii, O dagba ni Nasarẹti, O ba awọn ọmọde miiran ṣere; O ba baba Rẹ ṣiṣẹ; nigba ti O si di agbalagba, O bẹrẹ si i waasu ihinrere. Otutu mu Un, ebi si pa A—

ijiya ti ara; a fi I ṣe ẹsin, awọn miiran ninu awọn ọrẹ Rẹ timọtimọ ati ẹbi Oun tikara Rẹ ko si gba A gbọ́--irora ọkàn; nigba ti O si wà lori agbelebu, ti Baba mu oju kuro lara Rẹ̀, Jesu kigbe, “Ọlọrun mi, Ọlọrun mi, ẽṣe ti iwọ kọ̀ mi silẹ?”--ijiya ti ẹmi. O la gbogbo ìṣẹ́ oro wọnyii kọja ki Oun ba le jẹ “ Balogun igbala wọn”, Aṣiwaju gbogbo awọn eniyan ti wọn fẹ lọ si Ọrun. Oun jẹ Ẹni pipe tẹlẹ, ṣugbọn O jiya awọn nnkan wọnni ki awa le gbagbọ pe O mọ aini ati wahala wa. Lẹyin naa O kú ki O le jiya ẹ̀ṣẹ, “pe nipa ore-ọfẹ Ọlọrun ki o le tọ́ iku wò fun olukuluku enia” (Heberu 2:9). O ṣe gbogbo rẹ̀ fun iwọ ati emi. Bawo ni a ba ti fẹ Ẹ tó!

**A ṣe E Logo.**

Awọn angẹli ni Ọrun ṣe Jesu logo fun ikú ifararubọ Rẹ̀. Johannu ri ifihan kan ni erekusu Patmo “ẹgbãrun ọna ẹgbãrun ati ẹgbẹgbẹ̀run ọna ẹgbẹgbẹ̀run” angẹli, wọn n wi ni ohùn rara pé: “Yiyẹ li Ọdọ-Agutan na ti a ti pa, lati gbà agbara, ati ọrọ̀, ati ọgbọ́n, ati ipá ati ọlá, ati ogo ati ibukún.” Ati ju bẹẹ lọ, “gbogbo ẹda ti o si mbẹ li ọrun, ati lori ilẹ aiye, ati nisalẹ ilẹ, ati irú awọn ti mbẹ ninu okun, ati gbogbo awọn ti mbẹ ninu wọn, ni mo gbọ́ ti nwipe, Ki a fi ibukún ati ọlá, ati ogo, ati agbara, fun ẹniti o joko lori itẹ́ ati fun Ọdọ-Agutan na lai ati lailai” (Ifihan 5:11-13). Bi a ba fi tọkantọkan fẹran Oluwa ni tootọ ti a si n lo igbesi-ayé wa fun Un, ni ọjọ kan a o darapọ mọ́ awọn ẹgbẹ́ nla nì lati jumọ kọrin iyin si Jesu, Olurapada wa.

**Ẹbí Jesu**

Ifẹ Jesu ni pe ki a mọ Ọn pẹlu awọn eniyan Rẹ̀. Oun fẹran wa to bẹẹ ti O fẹ lati maa pe wa ni “arakunrin”. O fẹ ki a jẹ apakan ẹbi Rẹ̀. Nigba kan Jesu wi pe: “Ẹnikẹni ti o ba nṣe ifẹ baba mi ti mbẹ li ọrun, on na li arakunrin mi, ati arabirin mi, ati iya mi” (Matteu 12:50). Bakan naa ni a tun n pè wa ni ọmọ Rẹ nitori a bi wa nipa ti Ọlọrun, “bi awa ba si jẹ ọmọ, njẹ ajogun li awa, ajogun Ọlọrun, ati ajumọjogun pẹlu Kristi; biobaṣepe awa bá a jiya, ki a si le ṣe wa logo pẹlu rẹ̀” (Romu 8:17).

Ki a ba le jẹ ẹbí Jesu ki iṣe kiki pe a gbọdọ ni igbala nikan ṣoṣo, ṣugbọn bẹẹ gẹgẹ ni a gbọdọ sọ wa di mimọ́. Jesu ni Ẹni ti n sọ wa di mimọ́, ati “ẹniti nsọ-ni di mimọ́, ati awọn ti a nsọ di mimọ́, lati ọdọ ẹnikanṣoṣo ni gbogbo wọn: nitori eyiti ko ṣe tiju lati pè wọn ni arakunrin” (Heberu 2:11). Mimọ́ ni Ọlọrun, bi a ba si jẹ apakan ẹbí Rẹ, a gbọdọ jẹ́ mimọ́ pẹlu. Lẹyin ti a ba ni igbala, ti a ti dari awọn ẹ̀ṣẹ wa ji wá, a le fi ara wa rubọ jinlẹ si i ki a si gba Ọlọrun gbọ́ fun iriri ologo ti isọdimimọ́. Nigba ti O ba fun wa, Oun yoo mu wa mọ̀ pe a ti wẹ wa mọ́ laulau pẹlu Ẹjẹ Jesu.

Ẹbí Ọlọrun, awọn Onigbagbọ ti a tun bi ti a si sọ di mimọ́, maa n gbadun ajọṣepọ ara wọn, wọn si maa n mọ ifẹ Ọlọrun si wọn gẹgẹ bi baba si awọn ọmọ rẹ̀. Oun ko jẹ fi awọn ti Rẹ̀ silẹ tabi ki O gbagbe wọn lae.

## AWỌN IBEERE

1. Ki ni ṣe ti Jesu fi ni lati kú?
2. Nigba wo ni Jesu yoo di Ọba awọn ọba?
3. Bawo ni idajọ ti le to labẹ ofin?
4. Sọ diẹ ninu awọn ikede ti Jesu ṣe nigba ti O wà ni ayé?
5. Lọna wo ni a mu Jesu rẹlẹ ju awọn angẹli lọ?
6. Sọ diẹ ninu awọn ọna wọnni ti Jesu gba jiya?
7. Ki ni ṣe ti awọn ẹgbẹẹgbẹrun angẹli fi n kọrin bayii: “Yiyẹ li Ọdọ-Agutan na”?
8. Ta ni i ṣe “arakunrin,” “arabinrin” tabi “iya” Jesu?